**Owe**

KITA-KITA KOMỌ TI ARISIKI, KI A ṢISE BI ERU KO DA NKAN

# ELETI OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LEJO

**Asoje**

ENIA BI IYA KESI TANI JẸ ṢỌMỌ ỌLỌMỌ LORE.

VOL. XIII No 707 LAGOS SATURDAY SEPTEMBER 23, — SEPTEMBER 29, 1961. KỌBỌ MEJI (2D)


## OFO NLA SE! ALAKOSO EGBE MAJEOBAJE ABGAIYE (U. N. O) PADE AGBAKO OKO OFURUFU.

Ọgbeni Dag Hammarskjoeld, ti iṣe akọwe ẹgbẹ Majẹobaje Agbaiye ni a gbo wipe o ku ninu oko Ofurufu ti o wo nilu Leopoldville pelu awọn iṣangbe re ati awọn osise enia marun ti o nsise ninu oko na ni gbogbo won ku ayafi enia kan ti nwọn ri gbe ti koiti ku tan ni won yara gbe lọ si Ile Iwosan ilu Ndola.

Gẹgẹbi adehun, nigbati nwon nreti re ti nwon ko ri lati wa pade Alakoso ijọba Katanga, Moise Tshombe lati sọro didasija duro nilu Katanga ni aru bẹrẹsi fu won, ni won si bẹrẹ si fi awọn okọ Ofurufu wa ọkọ ti o wo na, ki nwon to lo ri ibi ti oko ofurufu re ti jalulẹ niwon ibuso mejc-abọ silu Ndola, Ariwa ilẹ Rhodesia.

Awọn ogunna gbongbo ẹgbẹ Majẹobaje Agbaiye (U.N.O) ti se ipade lati lẹṣẹ aṣaro lori eni ti yio rọpo Ologbe Dag Hammarskjoeld, ẹniti aye rẹ yio soro lati ri enia si ipo ra.

Ninu ipade na, eniti nwọn panupọ mu si ipo Ologbe na ni Ọgbẹni Mongi Slim, enia dudu ti ilẹ Tunisia ni yio wa ni ipo Alakoso ẹgbẹ Majẹobajẹ Agbaiye (U.N.O.)

Gbogbo ilu agbaiye ni awọn Olotu ati Alaṣẹ ijọba ti kowe sọrọ iwuri pupọ nipa Ologbe Dag Hammarskjoeld.

## Omuwẹ Omobinrin Oyinbo



Arẹwa ọmọbinrin ti a nwo ni u aworan yi ni Omidan Liz Ferris, ti o nkọ iṣẹ Onṣegun ni Ile Iwosan Middlesex, nilu London.

On ni o gba golu meji gẹgẹbi ohun ami iyege rẹ fun mimu okunkun ninu omi, ni ere idije omuwẹ ti nwọn ṣe nilu Ṣofia, Bulgaria laipẹ yi.

## Ibukun Ni Iranti Oku-Orun

EKO -- Iyafin Ayọ Potts-Johnson se isin iranti oku baba rẹ Ologbe Alufa E. K Ajai-Ajagbe ninu ile Isin ti Methodist ni Ereko ni owurọ ọjọ ọsẹ tokọja, ọjọ kẹtadin-logun oṣu September yi.

Eyi jẹ isin iranti ọdun kejila ti Alufa na ti f'aiye silẹ, ọsẹ awọn ebi, ọrẹ ati ojulumo ni o pe ṣiba-ṣiba. Alufa J. Shodipọ ti o ṣe isin na a sọrọ iwuri pupọ lori oku ologbe Alufa Ajai-Ajagbe.

Lẹhin isin ni Iyafin Ayọ Potts Johnson fun ọpọ enia ti o le nigba ni konigbagbe onjẹ adidun jẹ ni ajẹtẹrun l'owurọ ọjọ na ni ile re ni No 31 ati 33 Jhonson St, l'Eko.

Ki Oluwa f'ọmọ rere gbẹhin gbogbo wa o.

## Manager U.A.C. Lọ Si Ilu Oba.

Ni ọjọ kọkandilọgbọn oṣu August 1961 ni a gbọ ẹnu awọn ẹgbẹ Oniṣowo U.A.C. ti yan Ọgbẹni W.O. Olotu ti o jẹ ikan ninu awọn Oga ni ibi'ṣẹ wọn ni Ile-Ifẹ lati lọ si ilu Ọba.

Fun akoko ti Ọgbeni W. O. Olotu yio fi wa ni ilu Ọba, yio iṣẹ fun igba diẹ diẹ ninu ile iṣẹ U.A.C. ni ilu London. Ninu ile iṣẹ rira ohun jijẹ ati mimu, ni ile iṣẹ Asasari, ile iṣẹ Bata, ile iṣẹ Ogun fun irugbin oko ati ti Orun didun fun ikunra ati lẹhin na yio si tun ṣiṣẹ ni ile iṣẹ aṣọ ati awọn ohun meremere miran.

Ni ipari rẹ, yio kọ bi a ti ijẹ Alabojuto Agba ni ibi iṣẹ (Supervising Managers' Course) ati pelu yio si tun kọ ẹkọ ninu Tack Sales ki o to pada si Nigeria.

## Ojojumo ni Awon Oyinbo Gesi Nse Awari.



Ewo awon kanni robo-robo ti o wa ni atelewo ti a nwo ninu aworan yi, je ogun kan ti nwon tun sise se awari re fun iwosan arun awa eda enia l'aiye.

Nwọn ti se irufe re kan ti nwọn fi ngun abere fun enia ni'le Iwosan, boya gbegbemi ni eyi yio je, akoko mo.

## Alaga U. A. C. Lo Fun Isimi Ni Ilu Oba

ỌGBENI J. B. Davies, O. B. E. eniti Alaga ti ẹgbẹ awọn oni ṣowo ti United Africa Company of Nigeria Limited yio lo si Ilu Ọba fun osu mẹta ni ogunjọ oṣu yi fun isimi. Ọgbeni N. W. I. Kay lati ibi iṣe U. A. C. ni Ilu Ọba ni yio dele de e.

Ọgbeni Kay ki ise ajeji ni ile wa. O ti wa nihin ri fun ọdun merinla lati 1930 ti ti di 1944; ehin igbana o lọ si Gost ti a npe ni Ghana nisisiyi fun ọdun meji. Otun pada wa sihin ni 1946. Ni ọdun 1948 ni o pada si London lati ma bojuto ibi iṣe U. A. C ti a npe ni Nigeria Department.

Ọgbeni Kay pelu iyawo re ti o de sihin nisisiyi wọn yio si be awọn Agbegbe meta ilẹ wa wo lakoko igbati wọn ba wa nihin.

## U.A.C. Ran Awon Onise Owo Merin Lo Si Ilu Pakistan Fun Eko Ilosiwaju.

Awọn ẹgbẹ Onişowo ti a npe ni The United Africa Company of Nigeria Limited yio ran awọn oşişẹ wọn merin ti wọn nşişẹ ni Vehicle Assembly Plant ni Apapa lọ si ilu Karachi ni ilẹ Pakistan fun oşu mẹta. Tẹli ni Ilu Ọba ni wọn ti ma nran awọn onişẹ be lọ şugbọn awọn mẹrin yi yio lọ si Pakistan nitori Ẹrọ ti wọn nlo ni Pakistan dabi eyi ti o wa ni apapa.

Oruko awọn Ọgbẹni na ni: E.C. Anyalewechi, C. Onuba, L.D. Onukwu ati J.O. Gbokoyi.

Ogbẹni Anyalewechi jẹ ọmọ ọdun mẹtalelogun. O ko işẹ bi a ti ikan Ara ọkọ ilẹ ni Government Trade Centre ni Yaba. Osi gba iwe ẹri meji fun ẹkọ rẹ.

Ọgbẹni Onuba kọ işẹ irin ni Government Centre ni Ẹnugu fun ọdun mẹrin. O si gba iwe ẹri meji ninu işẹ na. Ọmọ ọdun meji-le ogun ni işe.

Ọgbẹni Onukwu jẹ omo ọdun mẹtalelogun. O kọ işẹ kikan Ara Ọkọ ilẹ ni Government Trade Centre ni Yaba. O si gba iwe ẹri işẹ na.

Ọgbẹni Gbokoyi bẹrẹ ise ni pẹlu U. A. C. ni 1951 gẹgẹbi Store boy a si gbe e si ipo Assistant Technical Storekeeper ni ọdun 1959. O jẹ ọmọ ọdun mọkanle-lọgbọn.

Awọn Ọgbẹni mẹta wọnyi: Anyalewechi, Onuba ati Onukwu bẹrẹ işẹ Pelu Vehicle Assembly Plant ni Apapa ni kete ti işe bere nibe ni 1959; sugbọn a gbe Ọgbeni Gbokoyi wa si ibe ninu ọdun 1960 lati Niger Motors Limited.

Nigbati awọn Ọgbeni wọnyi ba wa ni ilu Karachi awọn egbe onisowo ti a npe ni Dever Brothers (Pakistan) Limited ni yio ma se itọju wọn.

## Enia Dudu Mba Won Wonle Ninu Oko Ofurufu



Ijoba ilu Apapọse ti Rhodesia ati Nyasaland lalpẹ yi gbo ise ile wiwọn fun awọn Oyinbo Alagbaṣe iṣẹti nwọn npe ni Tairey Air Survey ni ilu Rhodesia ile repẹte kan ninu ile ise Apapọse ijoba won

Ẹni dudu kan ti o nşişẹ ninu ile ise awọn Oyinbo na nilu Salisbury ni a nwo aworan ile ti won na.

# ODUN ORUNMILA

(Lati Ọwọ Ọgbẹni Gbadebo Dosunmu)
Olulana, Ijo Ti Afrika ) Ọrunmila ( W. A. ).
Ẹnwọ Ya ( Mẹta ) Ayagbo. Ay tọ ( Mẹta ).

"EFIN, i nsọ,u ọmọ Pe rrete, Ọba bi elo l'eba ona, o nṣe Idi Wereke-Wereke; Ad'ifa fun "Layorj." Ti ṣe iyi Ejigbe l'ọjọ ti wọn nf'ẹnu ati wi irẹ. Nwọn ni bi nwọn kere lọ l'aiye, jọ lọrun, T'gọgọ ni nyọ'ri ju Gbamgba t'ọpọ Y'ọriju; Gbamgbi, T'ọpẹ Y'ọriju Gbamgba Tọpọ T'ọpẹ Y'ọriju, [Gbamgba'".

"ỌPẸ" Ig owo Igi Aiyera ye Igi apọ Igiti I-pọ pọ pọ ( Papa nino Ike awọn nọ-Jesu Aiọrọ aye Iti tọka si Iwe pataki meji ti wọn tọka si Igi Ọpọ iyi pe:-Iduro re yi D bi Igi Ọpẹ Orin Solomon 7, ẹsẹ 8; at Orin Dafidi 92 ẹsẹ 12 wipe Oledodo yio m gtag bi Igi Ọpẹ) Bi Igi ọpẹ ti ngba ri Olododo yio ma gba. Eyiyi tun fihan wa bi Igi ọpọ ti jẹ Igi Pataki t. ni Ayika Aiye.

Igi owo Igi ti O iye lori ni ọpẹ lara igi ọpọ ni Epe jijẹ ti nwọ, Ileke Jigida idi Igbale Igbọnlẹ Agbọn Ago A iẹ Papasan, Ogunsọ ọrọro funfun Adi, Ẹmu Ikọle atu'l bẹ-bẹ ma lọ Igi ọpẹ yiyi na ni Ẹgbe Afe i-Fẹrẹ mu ti nwọn fi ṣe Ami Ẹgbe n ọn. Beni ọmọ ti o ba juba Baba re gbogbo ohun ti o ba nse ama gun regeregẹ, iwa re a tutu pẹsẹ-ese Orunmila ni oba Aiyeraiye. Ami re si ni ọpe lodo Baba Ọrunmila ni "Aziri.Ile-Ilegbon" (King Prefect In The House of Wisdom) Ọlọpe kan Tosanra Dogi-Dogi, on ti ọmọ Arin ti nrin'de owo saka-saka, Awon ọmọ re ni "Ẹgbe Afeni-fere".

Iyoku di ose tombo

# Asiwaju Egbe Osise Ilu Malta



Ọgbẹni Dominic Mintoff, ti ṣe asiwaju awọn egbe osise ni ilu Malta ti nwọn yan si ipo Igbakeji Olotu ijọba ati Alaṣe awọn iṣe ijọba nigbati awọn egbe re (Labour Party) gba ijọba ninu ọdun 1947.

Lehin ibo ti odun 1955, Ọgbẹni Mintoff di Olotu ijọ'a ati Alaṣe nawo, ni asiko nwọnyen o nfe ki ilu Malta farat ọ ilu Oyinbo Gesi.

# Asia Titun Ti Oba Yio Lo Fun Abewo Ilu Saro



AWORAN asia ti a nwo yi ni ey ti Sir George Beher te fun Ilo Alaiyeluwa ( ba Obinrin ilu Gesi ni es ko abẹwo rẹ ni ilu Saro ninu ọdun yi.

Nbkb ti Ọba ba wa ni eo ma ri asia yi, yala ninu mote, tabi ninu ọkọ oju omi ati inu ile ti ẹba ba wọ si, ni ilu Saro

Eyi jẹ asia ti ko fun iranti abẹwo oba nilu Saro.

# Obinrin Abileko W'ewon Fun Esun Tete Tita.

EBUTEMETTA - Ọmọbinrin abileko kan ti o njẹ Dora Frances, ti o ngbe 21, Layinka Street, ni Apapa ni nwọn muwa siwaju adajọ lori esun ata tete, adajọ sọ s'ewon osu kan, o sọkun waiwai nigbati o jade kuro ninu apoti, o be adajọ ki o jowo ki o fun on ni ijiya miran yatọ si ewọn ṣugbọn adajọ ko gba.

Ẹnikan ti nwọn ju sewọn pulu obinrin abileko na ni Chiko Ajumọgbe ti on pelu re jijọ nta tete.

Ninu Kotu miran ni Ebute-Metta ni nwọn ko enia Metalelogbon ni Apapa. Ajegunle ti adajọ sa wọns'ewon oṣu kọkan tabi ki nwọn san owo nun meje ati ṣile mewa fun enikọkan lori esun tete tita bakanna.

# IROHIN IGBOMINA

(O bere ninu iwe ọse to koja)

Mofe bere lowọ ẹnyin ọmọ ẹgbẹ N.P.C. Olomi to wa ni N.A. Ilorin, wipe iru iwa tayi bi o ba jẹ wipe ẹnikan ninu ọmọ ẹgbẹ Igbomina Parapọ lo hu, kini ra ti ẹfẹ fi da ? Sugbon ẹyin ko wa tẹ ile aiye ẹfẹ bajẹ ni. Ṣugbọn atokere lati nkegbe ma ti ọpa bemi loju". Bi ẹ ba ti ẹwọ bo ara Oke-Ọddẹ leeu, wou yio gba yin jẹ de bi pe aromodomo yin yio ma ba ribẹ. Ṣugbon o ye ki ẹ pa iro inu yin ẹdọki inu yin ki ẹ sẹ asaro lori ọro awon ọmọ ẹgbẹ N.P.C. Olomi - aran iru ejo ti o ba ye ki ẹ da fun won o.

Ẹnyin ọmo ẹgbẹ Igbomina Parapo. Ẹ jowo mo ni alaye diẹ lati fi gba yin ni yanju. Owe awon Baba wa kan so bayi wipe "Korowo to pa Ọmọ ẹṣin. O nbọ wa ra ọmọ enia. Sugbon owe keji tun sọ ba i wipe Bi ọmọde ko ba mọ ẹwe a fi han ni. Ohun ti wipe iru nkan ti awon ọmọ ẹgbe Olomi N.P.C ṣe fun Mr J.G. Ẹkunrin ni Omu-Aran o jẹ nkan ijoju, Ṣugbon, ju gbogbo re lo ki iṣe Oddo ọmọ ibilẹ lo le dawo.

Bi ki base. Awon ti won gbewa si ile Igbomina, gbogbo awon ti won danwo. ti won lo ko ckuta dina fun enia ti nwọn si nju moto re ni okuta. Mo re i e roju ki ẹ fi oju ro ọrọ na Ẹ ma ṣe kọ re ọkan ara. Adura mi si Ẹgbe Igbomina Parapọ (Action Group - Alliance ni wipe Gbogbo wa pata pata. Lọkunrin wa ati Lobinrin wa. Oluwa yio ti wa gbe Arafa ti a nto. koni ja mọwa les; e ṣami aṣeo.

( Wo yoku loju ewe karun )

OKU'JA WOLU

NIBGA TI OJA KO BA TA, TI ẸNITI ONRA OJA KOTA EYITI O RA, BAWO NI YIO TI ṢE LE RA OMIRAN, EYI NI OGUN TI ONIṢOWO LE ṢE TI OJA RE YIO FI MA TA BI IṢU AKARA GBIGBONA.

E Polowo 0ja Nyin
Sinu Iwe Irohin
ELETI-OFE

## Emi Na Mo Ofin Pelu.

Onitsha — Ninu Kotu adajọ ke ere ni'u Onitsha ni okunrin Hausa kan ti nwọn fi sun ẹsun mẹta wipe o ji awọn apo iresi, ẹwa, tumati ati ewujẹ ti ti owo rẹ to ogun pọnun, ti o jẹ ti obinrin onisowo kan ti oruko re nje Theresa Okonkwo. ri o wi fun adajo wipe ki i se awọn adajọ agba ati adajọ kekere nikan l'o mọ ofin, enikẹni mo ofin, nwọn si le tumọ ofin ati on paapa

Okunrin Hausa ti nwọn fi sun ẹsun ole na njẹ Sali Gasuba, on ti i o d'ẹrin pa kotu ni lu Onitsha laipe yi, Kotu da lebi, adajo si ju s'ewon osu kan.

## Awon Agbe Ile Rhodesia Nko Ise Fifi Ero Roko Ninu Oyinbo



Ọgbeni Nyamwanza, okan ninu awon agbẹ roko medogun ti o ti lo ajumọsepo ijoba Rhodesia ati Nyasaland wa si ilu Oyinbo lati wa kọ bi awon ti se nfi ẹrọ sisẹ oko riro ati ohun ogbin ni a nwo ti o duro ninu aworan yi ti awon Oyinbo meta nse alaye ise ero fun.

,Ọse mefa ni awon agbe ile Rhodesia ati Nyasaland na yio fi opolopo oko awon Oyinbo Gesi wo lati ri iseti ero nse ati bi nwon ti se ngbin awon ohun ogbin.

# IROHIN IGBOMINA

( O bere loju ewe kerin )

Gegebi Owe mi ti mo npa fun yin telętelę wipe. "Bi ilę ba ngbe ęsika biko gbolotọ, Ore asuniṣe" ṣugbọn E maṣe jęki Orę yin rara gbogbo wa lao goke odo ki arafa to ja o. Amin ati aṣẹ o Adura mi si yin nipe gbogbo Eyin ọmọ ilę Igbomina. Lokunrin ati lobinrin Oluwa Olodumare yio dawa lare lori re yio si yọwa kuro ninu Oko ęru o. nitori ako gbọ ninu itan wipe Hausa niwa lati iṣędalę wa.

Enyin ọmọ Egbę N.P.C. Olomi mo nreti awọn esi ọrọ mi yi pelu alaye kikun. Lati ọdọyin. Morsii nomọ daju wipe E ko gbero lati kuro loko ṣugbọn adura mi ni wipe ki Oluwa tete ṣdayin pada si ilę Baba yin Mofę ki ę mọ daju wipe ijọba N.P.C. ko gbero ire fun enyin ọmọ Igbomina, to ba wa ninu Egbę wọn, ọrọ kopọ ęo tun ma gbọ iyoku ni ọsę to mbọ.

## Awon Aringba-nraye W'ewon

EBUTEMETTA - Awọn enia merin ni awọn ọlọpa muwa siwaju adajọ ni Kotu Ebute-Metta fun ęsun irinkiri l'ora ti o mu ifura dani wipe nwon le ję ole.

Awọn ędaran na niwọnyi 1, Adio Adegbọla 2, Amodu Suberu, 3, Sule Aiki ati 4, Ladipọ Adebogun. Awọn ędaran na ti sọ wipe awon jębi, adajọ si ju gbogbo wọn s'ęwon oṣu męta-męta fun ęnikọkan.

Adio ati Ladipọ ti o ti lọ bi ęmęfa ati ęmęrin ri, ni adajọ fi bulala męta-męta kun ti wọn.

## Itan Ajapa Ati Eiye

( O bere ninu iwe ọse to kọja )

Bi o ti ri s'nu omi ni o pade iyemọja Oriṣa odo. Iyemọja bere pe ki lo nfę lati kini o gbe de ibi ?. O si ko ęjọ bi o ti ṣe de, oro fun oriṣa odo. Iyẹn ni ki nwọn fun ni awo alarabara kan, wọn si ṣe alaye bi yio ti ṣe awo na fun u. O ni ti o ba de le ki o ti ilekun mọri, ki o si bere iṣę kini awo nṣe ? Awo na dahun pe on ami ba onjẹ ea ti ebi npa, onjẹ yio unle repetę.

Inu aja dun tobẹ to fi jo pe Olu ako wipe on fę bọ gbogbo ilu fun ọdun kan, Ọba dahun pe Ajapa ti kori onje je ni o ma wa bọ gbogbo ilu fun, ọdun kan ọba ni ki awọn lọ mu Ajapa wa wọn si mu'de, ọba bere pe kini o fe se fun gbogbo ilu? Ajapa dahun pe mo fe bọ wọn ọba ni o da ọ loju o ni o da on loju ati imu papa.

Ọba ni ti o ba di ọjọ meje ki o wa bo ilu ki awọn ri. Igbati o di ọjọ keje, gbo-gbo ilu ti pe wọn si nreti Ijapa beni Ijapa yọ pelu awo alarabara ti o si fi ni ki onilu ma ki on hayi, Ajapa tiroko ọkọ yanribo.

Ajapa ti o fe bọ ogun-bolu duro ki won ma wo ohun ti on fe ṣe e. Ajapa gbe awo sile o ni iṣe kini awo nṣe ? Awo ni ohun nkọ onje fun awon ti fun awọn ti ebi npa, o si ko onje sile repete gbogbo ilu je won yo ibiti won ti ndu onje je, won ko lu awo o si o si fọ.

( Iyoku di ọse to mbọ )

## Ile Ise Ero Alaworan Tilu Oyinbo Kora



Ilkedo fun agbaṣe iṣẹ ile erọ Alaworan Asọrọmagbesi ti ilu awon Oyinbo Kọra (Lebanese) ni o bọsi ọwọ Alagbaṣe iṣẹ tilu Oyinbo ti awọn ni Marconi's Wireless Telegraph" lati kọ ile iṣẹ na

Awọn ọpọlọpọ Alagbaṣe iṣẹ (Contractors) l'o kọwe ki ti ilu Oyinbo Gęsi to yege. Ọkan ninu awọn erọ asọrọmagbesi alaworan (Television) ti nwọn yio fi ranṣẹ si ile iṣẹ na ni a nwo ninu aworan yi.

See the fabulous new
KELVINATORS
at

LEVENTIS
TECHNICAL

MARINA. IDDO
IBADAN. KANO
JOS. P. HARCOURT
ABA



Model K94M

CAPACITY
9' 4 CU. ft
PRICE £115
H. P. TERMS AVAILABLE IN
LAGOS AREA ONLY

## Ise Gbe Ogbeni Akinwale Lo Si Saria.

oo———o:———o:———oo

EBUTE-MẸTTA - Irohin ko to af'ojuba nibi apejẹ onjẹ kan ti awọn bọrẹkini ẹlẹgbẹ Ọgbẹni N. A. Akinwale t'le iṣe Reluwe ni Ebute-Metta fi ṣe idagbere ki Ọgbeni Akinwale nigbati iṣe ngbe lo silọ Zaria nile Ariwa, Oke-Ọya, ni Opopo Queen, ni Yaba.

Ọgbeni M. A. Ajala, ọga nibi iṣe Reluwe, (Traffic Inspector) ni o ṣe Alaga. Ọgbeni A. A. Mayan ti ile iṣe Town Council l'Eko sọrọ iwuri nipa Akinwale depo ti o fi sọ wipe, Ọgbeni Akinwale je eniti o ni iwa ti o ye ki enikeni maa ṣe afarawe re.

Ọgbeni Akinwale f'esi dupe lọwọ awọn ọre re ti o fi ase na da on lọla, o si ṣe ileri wipe on yio gbiyanju lati se gegebi ireti wọn nibikibi yio wu ti on le wa.

Awon enia pataki - pataki ti o peju-pese nibi ayẹyẹ na ni Ọgbẹni J A. Bologbo'pa, J.A. Adeyẹmọ, F. O. Ọnanuga, ti o fi nken imoti ọjọ na le Ọgbẹni Akinwale lọwọ, J.T. Ọlaluwoye Phillips, S.B. Roberts, H.S. Peters, T.O. Obiwunmi, T S Agbabiaka D.O. Agusiogo, F. T. Odugbesan, A.A. Eketunde ati A. Ṣoetan.

DO ALL YOUR SHOPPING
AT
Messrs J. H. DOHERTY LTD
Department And
SUPERMARKET
BANUSO STORE
80/88 BROAD STREET, LAGOS
FOR QUALITY, VALUE & SERVICE
( OPPOSITE THE CENTRAL BANK AND
NEW B. O. A. C. OFFICES )

E Ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe

Printed & Published By The Union Printing and Publishing Company 28, Kọsọkọ Street P.O. Box 467 Phone No 23370